# IWE SI OLOTU

## IBOOSI OLE!

OLOTU inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye lati ke si awọn Ọlọpa lati ba wa se abojuto awọn ole ti o wa ni adugbo Fọkọ Ibadan awọn ọlọsa wọnyi ko si fuu wa ni ifọkanbalẹ rara ati papa fun wahala ti awọn ole na ma nfun wa l'oru oganjọ ti nwọn ko ni jẹ ki agbadun ti a ba ti sun ni alẹ ati papa julọ fun ọpọlọpọ awọn enia ti awọn ole na ti sọ di talaka patapata.

Inu wa yio dun bi awọn Ọlọpa ba le ba wa ṣe amojuto awọn ẹhanna ọlọsa wọnyi.

Eyi to si tun buru julọ ninu iwa ti awọn ọlọsa na nhu nipe nwọn ma nko ile awọn enia to ba ti lọ si bi iṣẹ lati owurọ titi di ọsan tabi irọlẹ to si jẹ pe nwọn si sọ awọn enia wọnyi di alakisa.

Inu wa yio dun bi awọn Ọlọpa ba le ba wa ṣe abajuto awọn ọlọsa na

Mo dupẹ o Olotu ajinde yio ma jẹ.

Emi ni
Johnson Akinola
IBADAN

Oro ṣugbọn ẹ jẹki a gbagbe ohunti o ti rekọja nitoripe ti a ko ba gbagbe Oro ara a ko ni ri eni ba ṣere.

Ẹ jẹki a ranti ẹhin ọla ki ama ṣe ba nkan jẹ fuu awọn ọmọ wa ti nbọ lẹhin, nitori gbogbo nkan ti a nṣe lori itan ni lẹhin ọla aiye siti di aiye oyinbo oju ti la kosi ọbọ ni idere mọ. Olotitọ ilu ni ika ilu. Bi a ba ba ara wa sọrọ, o yẹ ki a gbọ aabọ ọrọ to fun ọmọluwabi

Emi ni
Alakiyesi

## Olotitọ Ilu Ni Oṣika Ilu

Mbe ṣọpẹ bi olotu bale gba mi laye niwọn ba ranpẹ ninu iwe rẹ penpẹ bi aṣọ esiṣin lati ba alagba kan ọgbẹni Bello sọrọ lori eyeti o ti nja si ni ilu Ijọmu Ọrọ lati nkan bi ọdun diẹ sẹhin ki ole jawọ ninu ọrọ na, nitori pe bi ara ile ẹni ba njẹ kokoro buburu ti ako ba tete sọ fun un huruhuru rẹ ko ni jẹki asun loru.

O dara, o si tọ ki ọgbẹni wa Bello o ma wipe bi enia meji ba ndn Oye mọ ara wọn lọwọ ti o ba si ja mọ ẹnikan lọwọ, awọn yoku a mu surn lati di asiko ti wọn.

Nitorina, ki Ọgbẹni Bello lọ se eto ati ẹtọ larin agbo ile rẹ ati awọn Ọmọlẹbi Baalẹ lọdoogba, ki ede-iyede yi ki o le tete tan nilẹ kia kia ki o maṣe tun maa lọ siwaju mọ.

Bi a ba ni ki a sọ otitọ Ọrọ eo ri wipe, ẹnyin ni ẹ da edeaiye de na sile, ey ti o nja loni larin ilu Ijọmu

## Ọrọ Wo Ni ki Nsọ?

Inu mi yio dun pipọ bi Olotu ba le gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ ti nkọwa ni ọgbọn ati oye lati bere ọrọ mi yi lọwọ awọn to nka iwe na lojojumọ. Inu mi yio si dun ti nwọn ba fun mi ni o si to dara si ibere mi na. Ati pe inu esi ti mo le fun eniti o sọ pe, mo kere.

Ibere mi na lọ bayi, mo ran aburo mi si ọmọbinrin kan, ọmọ obinrin na si da mi lohun, mo ko mọ ro fun gbogbo nkan ti o fi wu mi mo wa pari ọrọ pe ọmọ fẹ fẹ sile tabi ki n jẹ iyawo mi.

Esi ti o fun mi ni wipe,, mo kere, oju si gbamiti fun iṣẹju marun agogo mi kole sọrọ rara, ni olukaluku ba ba ọna tirẹ lọ

Mo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ, ọrọ wo ni ki nsọ ọmọbinrin na

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi Olotu.

Emi ni
T. O. Alafẹ
IJỌMU.

## Ẹ ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Ki ẹ si ma Polowo ọja nyin Pẹlu

## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ki o wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo Eran Itirẹ

## Apejuwe Ile Isẹ Wa

Ẹ Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni ti oba sokalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | 20/- |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 25/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ilana Yanrin titẹ ati Etutu Şişe | |
| Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Isẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6 |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/6 |

J.O. Shoyinkan
c/o Postal Agen
Itirẹ Via Suru Lere,
Yaba.
or 1,Ishiba Street (Odo Ẹran)
ITIRẸ

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TONIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Toniki wọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan işẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ṣe şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa da ọkun lọsan tabi loru tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradarawọn iṣẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo enyi il ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun lọ si ded'adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ re s'i dan pada. Ara re yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igbadun ati alafia yio de si ọ. Iyen daju. Bere Egbogi na ni Şọbu:-

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Stree, Lagos.

# Ṣọọṣi Ẹnu-Ọwa Gba Kalẹ L'alejo

Irohin ko to afojuba ni ojo isimi to koja nigbati Biṣọpu Ijọ CMS L'Eko, Ẹni ọwọ Seth Irunṣewe Kalẹ lọ ṣe isin igbọwọleiori (Confirmation) afarinrin ni ile Ọlọrun Ẹnu Ọwa. Eyi ni igba kini ti Biṣọpu na yio wọ ile Ọlọrun yi.

Gbogbo enia ho iho ayọ nigbati Biṣọpu ati iya afin rẹ wọ inu ọgba ile Ọlọrun na, awọn ọmọ ẹgbẹ akọrin si nkọrin 'Alleluya ẹ gberin, Oluwa, lo yan ọ ki ṣe enia Alleluya ẹ gberin ni Kerubu gberin wa, Oluwa lo yan ọ ki senia ki Kerubu gberin wa"

Ni deede agogo mẹfa abọ ni isin igbọwọleiori na bẹrẹ Ninu wasu rẹ Ẹni ọwọ Kalẹ, kesi awọn ti ao gbọwọleiori lati wa ni imurasile fun ẹbun ẹmi mimọ O fi yẹ awọn wipe nwọn ni lati ni ọwọ mimọ ati aiya funfun nwọn ko si gbọdọ gbe okan wọn soke si asan ki ibukun ati ododo le ba le wọn lati ọdọ Ọlọrun igbala wọn.

Lẹhin eyi ni awọn merin-lelogun ti a ṣe isin igbọwọleiori fun to wa siwaju Biṣọpu ni meji meji.

Gẹrẹ ti a jade isin, awọn Ijọ ṣe ase ẹyẹ ' Ikini kabọ' kan lati ki Biṣọpu ati aya rẹ ninu ọgba ile Ọlọrunwọn Ọgbẹni Ọṣunlana asoju Ijọ tọka si Biṣọpu gegebi iranṣẹ Ọlọrun ti o wa lati tun Ijọ rẹ ṣe, O rohin gbogbo akitiyan rẹ, o si pari ọrọ rẹ pẹlu adura pe ki Oluwa ma se alatilẹhin rẹ fun un.

Ninu esi rẹ Biṣọpu Kalẹ ni a ti se ọpọlọpọ ẹyẹ ikini kabọ fun oun mse ti on je Biṣọpu ṣugbon eyi ko ni gbagbe ẹyẹ ti Ijọ Ẹnu-Ọwa ṣe fun on. O ki Ijọ na ku ori re nipa Alufa alakitiyan ti nwọn ni C ni alagba ni Alufa na sibẹ O nfi agbara ṣiṣẹ Oluwa O yin in fun ọwọ mimọ, ifẹ iwa irẹlẹ eti gbogbo laala rẹ ninu Ijọ ati

nipa iṣẹ iranṣẹ iran O rọ awọn Ijọ lati maa ṣiṣẹ lọ laijarẹ. si ni awọn ẹgọọ awa B ṣ.pu Ijọ n ta aya Biṣọpu l'ọrẹ ki g .. gbo ase eyẹ na pari ni agogo mẹsan abọ alẹ.

Gbogbo awọn Ijọ fun Bisopu na ni ẹbun bakauna

# Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun To Nbọ Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA" MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe "AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI" LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INA KUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA t'Oluwa ọwọ ṣe Isin Haii wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubor Ẹogbo ẹda patapata" Amin·

## WAS SALAM"

AKIYESI: Gbogbo Muoulumi Ododo lo ye ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA.

Iye O o 5/6 £3 fun dọsini

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET,
Ibadan

# IWE ITUMỌ ALA

Josefu Alala ti ẹ ti ẹkan ninu iwe Irohin Yorub ti jade ni ẹdindi fun tita nisisiyi.

OHUN TI O WA NINU IWE NA

1. Egbogi Ajẹbidan agbabiẹtu.
2. Odu Ifa mẹriodinlogun lati ma a fi yẹ itumọ ala rẹ wo.
3. Ẹnikẹni ti o ba fẹ ra iwe yi ni anfani lati bere ala rẹ nigba gbogbo lọfẹ lọwọ Josefu Alala.
4. Koiti si ikeji rẹ ninu iwe itumọ ala ti o ti njade ri nitoripe JOSẸFU ALALA ni o ṣe e

Tete ra tire loni ki o to tan.

AKIYESI

A tun nfẹ asoju ti yio ma ba wa ta iwe na, owo pọoku ni ao ta fun wọn ki nwọn ba ri ere gọbọi je ba fẹ se asoju wa kọwe fun iwe adehun,

Iye owo 5/- £2

**J. O. Shoyinka**
N/ Shittu Street
Ibadan

tabi
1, Isiba Street Odo Ẹran
c/o Postal Agent
Itire,
Via Suru—Lere,
Yaba

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 21-Feb 19) Ọrọ iṣoke ṣodo ọrẹ rẹ yi o jẹ ohun ẹdun fun ọkan rẹ maṣe gbe ọrọ na le ọkan rara

PISCES (Feb 20-Mar 20) Agbara awọn ọrẹ rẹ atiiọ yio pọ loni Iwọ y o si tun bere si ko awọn ọrẹ titun ọiọ

ARIES (Mar 21-April 20) Ọrọ ni pa ẹbi tabi ọrẹ yio ṣelẹ iwọ o si gbalejo kan loni inu rẹ yio si dun jọjọ loni

TAURIS (April 21-May 22) Idẹra ni Ọjọ oni jẹ fun ọ larin awọn ẹbi rẹ awọn ọdọ larin awọn ẹbi rẹ yio ma ṣe ere gele pẹlu awọn obinrin

GEMINI (May 23-June 21) Wahala ile ko ni jẹki ojoko sibi kan Ọjọ iranti ni yio siiẹ suru ni opin rẹ bi a ba nfẹ ki ile roju, ki ọna baye

CAUCER (June 22-July 22) Iwọ yio ri iranlọwọ lọnakọna ninu idagbasoke iṣẹ rẹ pataki larin awọn ẹbi rẹ ohun ayọ kan yio ṣelẹ nigba aṣalẹ ti yio mu inu rẹ dun.

LEO (July 23-Aug 22) Awọn alijannu yio bo asiri rẹ nipa idurosinsin rẹ ohun ayọ kan yio de si ọ wa aye lati simi tabi ki o fara lele.

VIRGO (Aug 22-Sept 22) Orun alafia yio tan lori awọn ẹbi rẹ loni Alejo kan yio wa bẹ ọ wo ere ayọ yio si de ṣugbọn maṣe yọ ayọ pọ pọ.

LIBRA (Sept 23 Oct 22) Maṣe ro ti ara rẹ ni kan rò ti elomiran pẹlu tirẹ mura silẹ ẹbun iyanu kan yio de si arin wọn ẹbi rẹ oyẹ ki o lo ọgbọn ori rẹ nibẹ

SCORPIO (Oct 23-Nov 22) Ayọ ati irẹpọ yio wa larin awọn ẹbi rẹ loni, bi Ọjọ ti nlọ si wẹju bẹ ni idagbasoke ngberu si larin awọn ẹbi rẹ

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Ayipada titun yio ṣelẹ larin awọn ẹbi rẹ irẹpọ yio gbilẹ larin nyin jọjọ yio si d bi eyi e da ẹgbẹ kan sile

CAPRICONUS (Dec 23-Jan 20) Alejo kan ti o mbọ wa ki ọ loni yio wa pẹlu inu didun ati ayọ.


# AKIYESI PATAKI!

Eyi ni lati kede fun awọn Onkawe IROHIN IMỌLẸ jakejado Ilẹ Naijiria pe ỌTẸLẸMUYẸ ti ti aio de nisisiyi. Ọrọ rẹ yio si ma a jade ninu IROHIN IMỌLẸ deede nisisiyi nitorina ki ọwọn onkawe ki wa mura silẹ lati ma ka igilango urọ ỌTẸLẸMUYẸ ti yio ma jade ninu Iwe wa na,

OLOTU

# Eyi ni awọn ọjọ Ọja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE MAY 11 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye,Ikosi, Ẹpẹ |
| ABEOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba lokuta' Ijaiye-Orile |
| IJEBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe sara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| IJESHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọọ Ilaṣẹ, Iperindo |
| EGBADO | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ IṢẸGUN MAY 12 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonkọ, Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun—Ọwa, Ẹruwọn, Omu, Mamu |
| JẸSHA' | Osnu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ'RU MAY 13 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege, Ebute-Ero Ọjọ Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA | Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ MAY 14 (THURSDY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Bẹrẹkodo, Aṣu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun Ṣagbẹ, Ogunjau, Mọlete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Shagamu, Itaoṣu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi-Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Oja-Ọdua, Sunwa, Iboro, |
| EKITI | Ilogbo Ishan. |

## ỌJỌ ẸTI MAY 15 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA | Atan Agbado, Ifọ Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹda Babalokuta, Ijaiye Orile. |
| IJẸBU | Ilishan, Isara, Imodi. |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọ. |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Oda. |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ ABAMẸTA MAY 16 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin Badagrey |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkọ Omida Itwọ |
| IBADAN | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa Eruwo Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idokọ Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owod |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AIKU MAY 17 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ Idọgọ, Olodo. |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imope |
| IJẸSHA | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo-Idlẹmi |
| EKITI | Okemẹsi, Ifaki. |

## ỌJỌ AJE MAY 18 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo Ejioris |
| ABẸOKUTA | Ijoko Ibẹrẹkodo, Asu, Wasnimi Owode |
| IBADAN | Akẹroro, Idọfin, Laguo, Sagb Ogunjana, Molete |
| IJẸBU | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Oja-Ọdan, Suwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Ọwọ EJO'NGBORO

### APAPA

Ọdaran kan ti awọn Ọlọpa mu, Adetọla Emmanuel ni o ti salọ mọ awọn Ọlọpa lọwọ ni Tẹsan bi nwọn ti gba ẹrọ silẹ lẹnu rẹ tan.

### EKO

Ọdaran kan ti o ki ọwọ bọ inu apo Oloye J. N. Johnson ni awọn Ọlọpa ti mu, nitori pe o fẹ ji owo Oloye na nibiti nwọn ti nṣere idaraya ninu Ọgba (K. G. V.) Onikan

### OYỌ

Enia kan lo ku bamubamu ti enia meji si fi arapa nigbati mọto akero kan takiti sinu gọta ni Ọna Ibadan si Oyọ

### ABEOKUTA

Ọgbẹni Lapitẹ, adajọ ile ẹjọ kekere ti ṣe idajọ pe ki awọn Ọdaran marun kan lọ fi ẹwọn Ọdun mẹdọgbọn juro nitoripe nwọn jẹbi ẹsun ile fifọ ati ole jija ti Ọlọpa mu wọn fun.

### LAKE-CHAD

Alhaji Abubakar Tafawa Balewa yio ṣe alakoso awọn enia Naijiria lọ si ipade pataki kan ti nwọn fẹ ṣe ninu ọsẹ to mbọ yi ni Lake - Chad.

### SEOUL

Enia merinla lo ku bambam ti enia mọkandinlogbọn si farapa nigbati ojo nla kan rọ ti o si wo ile pẹtẹsi alagbeka merin kan wa lulẹ.

### NAIROBI

Jiẹnijẹnu dabo gbogbo enia nigbati nwọn ji ni owurọ ti nwọn si ri wipe awọn kan ti lọ pa Ọgbẹni Markwood to o ti fi igbakan jẹ Gomina ilu na sinu ile rẹ Awọn Ọlọpa nwa awọn enia na lẹwọ.

### SYRIA

Ilẹ-ẹjọ awọn alaṣẹ ogun ti paṣẹ pe ki nwọn lọ yẹgi fun awọn ọmọ ogun mọkanlelogun nitoripe nwọn ditẹ si Ijọba.

### ONDO

Idamu nla ba gbogbo enia nigbati obinrin kan Iyaafin Adeikẹ Ilukun ṣubu lulẹ ti o si ku bamubamu ti obinrin kan Alice Moralayọ sare jade ninu ile ti o na si ku lẹsẹkẹsẹ.

### NIGOSIA

Agogo ṣọọṣi lo ji gbogbo enia nigbati awọn ọlọtẹ kan wọlu ti nwọn si apa enia bi igbati npa ẹran ileya

IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 602 MONDAY, MAY 11, 1964 (2D)

## AZIKIWE KILO FUN AWON ARA ILU

**EKO.— Olọla Naamdi Azikiwe, lo ki bosi fun gbogbo aiye gbọ wipe, eso di ọwọ awọn Aşiwaju Oşelu ti nwọn mbọ wa şe apejọ nilu Eko, ki ẹlẹnu pa ẹnu rẹ mọ ki nwọn maşe sọ pe bayi bayi ni apejọ na yio ri nitoripe ara nfu on wipe jamba le şẹlẹ ninu apejọ na, nitorina eso di ọwọ olukuluku.**

Işẹ temi ni gẹgẹbi Arẹ gbogbo ilẹ Najiria lati şe ikilọ fun gbogbo awọn ti o ba nfẹ işọkan ilẹ Naijiria lotitọ ati ododo li ọkan rẹ.

Emi ni kan gẹgẹbi Aarẹ ilẹyi ni mo ni aşẹ lati şe iru ikilọ bayi, nitori ki a ma ba sọ ara wa di kekere larin awọn Orilẹ-ede. Bi mo ba ri ewu bi iru eleyi ti o mbọ ti nko si tete yara ki bosi rẹ jade, emi yio jẹbi işẹ mi si ilu mi.

Nigbati a fẹ şe ofin ilẹ wa awa li a ki bosi fun araiye pe a fẹ di Republic (Ilu ti ọba ko gbọdọ paşẹ) lati fi han pe ẹnu wa ti ka awọn enia wa lati wa ni işọkan. Şugbọn ọrọ ti a ngbọ kakiri lẹnu awọn Oselu wa, ko mu wa gbagbọ wipe awọn enia wa ni ẹmi işọkan li ọkan iyapa ati aişe deede wa larin wa.

Nitorina, mo fi eyi şe iranti fun gbogbo enia wipe bi Alhaji Tafawa Balewa ba pe ipade apejọ na, ẹnikẹni ko gbọdọ sọ wipe nkan bayi bayi ni nwọn sọ ni ipade na, ayafi bi oluwarẹ ba jẹ Ọbalyejẹ, o yẹ ka fi Ọla fun ẹniti ọla nşe tirẹ

# AARA PA AWỌN OBINRIN MEJI PẸLU ỌMỌ LẸHIN

Jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati ojo nla kan bẹrẹsi rọ ti ko si da, ti awọn obinrin meji mbọ lati oko ti aara si san pa awọn obinrin mejeji ni oju ọna pẹlu ẹru ti nwọn ru lori ni Ohafia Agba ilu kan ni agbegbe Umuahia ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ni ọjọ ọjọ 'Bọ ti ise ọjọ kẹjọ osu yi.

Ẹniti ọranna soju rẹ şe alaye fun oniwe irohin wa wipe, awọn obinrin mejeeji na lọ si oko wọn lati lọ tọju nkan oko wọn ni, nitoripe awọn obinrin ni o nda oko ti awọn ọkọ wọn ma a mba ọmọ wọn şere nigbati iyawo ba lọ si oko.

Nigbati nwọn si şişẹ wọn tan, ni nwọn ba mbọ wale, şugbọn ko pẹ pupọ bi nwọn ti nlọ si ile ni ojo nla kan de ti awọn obinrin si nsare lọ si ile.

Şugbọn bi aara nla kan ti san ni o ba pa awọn obinrin mejeji na si oju ọna

Ohun ti o ya gbogbo enia lẹnu ni wipe ọkan ninu awọn obinrin na ti o pọn ọmọ lẹhin.

Nigbati aara na san, o pa obinrin na şugbọn ko pa ọmọ ti o pọn lẹhin, o si gbe ọmọ na lọ sinu oko kan ni ẹba ọna ti ko jinna si oju ọna bi ọgbọn bata ẹsẹ lọ. Ọmọ na si nsunkun nibẹ ti gbogbo awọn aladugbo ti de nigbati ojo na ti da.

Irohin fi ye wa pe, awọn ero ti o nlọ si oko nigbati ojo na da ni nwọn ri oku awọn Obinrin na ti nwọn ti ku bamubamu si ẹgbẹọna

Bi nwọn ti nwo awọn Obinrin na ni nwon ngbọ ẹkun ọmọ kan ninu oko ti o wa nitosi, nwọn si lọ gbe ọmọ na.

Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn lọ ti ọrọ han awọn Ọlọpa ni Teşan lati wa wo engmọ ti awọn ri.

Nigbati awọn Ọlọpa de, ni nwọn ba gbe oku awọn Obinrin na, şugbọn ki nwọn to şetan, awọn enia nwọn ti gbọ, nwọn si wa şe itọju omọ oku na.

Awọn Ọlọpa ti gbe oku awọn Obinrin na lọ si Ile-iwosan lakulaku fun ayẹwo awọn Dokita.

OLUWA RERE GBA WA LOWỌ IKU OJIJI.

---

Lati Oju Ewe Kini

tẹlẹ ki o to daoo ni Okunrin, gbogbo iwa ati işesi on ko ya ti Obinrin rara.

O tun şe alaye pe awọn obinrin na tiẹ tun sọ eyi fun on ni Ọpọlọpọ igba, on paapa na si tun şe akiyesi ọrọ na on ri daju pe otitọ ọrọ ni gbogbo Ọkuurin ti nwọn nsọ fun on.

Bi Adajọ ba ti pari rẹ si ẹo ma gbọ.

make it a successful SEASON with MERCEDES-BENZ TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor FUNJI ADKOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga 11/5/64